# OMI LATI INU APATA: IṢẸGUN LORI AMALEKI

## Ẹksodu 17:1-16

## ẸKỌ 59 – FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Awọn ti nwá Oluwa, ki yio ṣe alaini ohun ti o dara" (Orin Dafidi 34:10).**

### Ko si Omi

Gẹrẹ ti awọn Ọmọ Israẹli bẹrẹ lati tun tẹ̀ siwaju ninu irin-ajo wọn, ni wọn bọ́ sinu iṣoro miiran ti o mu ọkàn wọn rẹwẹsi -- kò si omi lati mu. Nipa aṣẹ Ọlọrun ni wọn fi n rin irin-ajo yii, eyi ti o fi hàn pe ọwọ̀n awọsanma ti kuro ni ipo rẹ̀ o si ti ṣi lọ siwaju. Bayii ni Ọlọrun n tọ́ awọn Ọmọ Israẹli ninu gbogbo irin-ajo wọn; "Nibiti awọsanma ba si duro, nibẹ̀ li awọn Ọmọ Israẹli idó si"; ṣugbọn nigba ti o ba ká soke wọn a tẹle e (Numeri 9:17). A mọ pe wọn wa ninu ifẹ Ọlọrun lati rin irin-ajo naa, ṣugbọn ọta paapaa wa ni tosi lati jẹ ki o sú wọn.

Bi Onigbagbọ́ ti n ya aye rẹ sọtọ fun iṣẹ Ọlọrun, lati tubọ sun mọ Kristi si i, bẹẹ ni yoo ri i pe Satani yoo fi ohun idena pupọ si ọna rẹ, yoo si maa sọrọ iyemeji si i leti. Oun ko fẹ ri i ki Onigbagbọ́ tẹ siwaju, oun yoo sa gbogbo ipá ati agbara rẹ lati de akikanju ọmọ-ẹyin naa lọna.

Nipa agbara Ọlọrun, Mose ti sọ awọn ẹrú wọnyii di ominira, eyi ti wọn i ba dupọ pupọ fun. Dipo eyi gẹgẹ ti iṣoro ba di de, wọn a fẹ pa a run. Wọn da a lẹbi pe o mu wọn wá si aginju lati kú.

### Omi lati Inu Apata

Mose mọ ohun ti o tọ lati ṣe lakoko wahala; o kigbe pe Ọlọrun. Oluwa wa nibẹ gan an lati da a lohun. O sọ fun Mose lati mu ọpa rẹ eyi ti o ti lò lati ṣe iṣẹ-iyanu ni Egipti, ki o si lọ lu apata ti Oun yoo fi hàn án, omi yoo si tú jade lati inu rẹ̀. Bi o ba ṣe pe Mose dabi awọn iyoku ti o kùn oun i ba wi pe eyi ko le ri bẹẹ, ṣugbọn oun gba Ọlọrun gbọ́, o si ṣe bi a ti palaṣẹ fun un. Ọlọrun wi pe Oun yoo duro ni iwaju rẹ̀ lori apata naa, boya ninu ọwọ̀n awọsanma gẹgẹ bi Oun ti ṣe nigba miiran, awọn agbaagba ti wọn tẹle Mose lọ yoo jẹ́ ẹlẹri iṣẹ-iyanu Ọlọrun ni mimu omi jade lati inu apata gbigbẹ. Iṣẹ-iyanu yii ṣẹlẹ gẹgẹ bi Ọlọrun ti wi, awọn eniyan si mu ninu odò naa, a si tẹ́ ọkàn wọn lọrun.

### Kristi Apata Wa

Paulu lo ohun ti o ṣẹlẹ yii lati sọ otitọ iyebiye kan nipa ti ẹmi fun wa ninu 1 Kọrinti 10:4 pe, "Nwọn nmu ninu Apata ẹmi ti ntọ̀ wọn lẹhin: Kristi si li Apata na." Lati inu apata naa ni wiwa laye nipa ti ara ti wá, nitori bi wọn ko ba ri omi mu, gbogbo wọn ni yoo ṣegbe. Bakan naa ni a ni iye ainipẹkun ninu Kristi niwọn igba ti a ba n mu ninu kanga igbala. Jesu sọ fun obinrin ni leti kanga pe omi ti Oun yoo fun un ko ni jẹ ki orungbẹ tun gbẹ ẹ mọ, yoo si di "kanga omi ninu rẹ̀, ti yio ma sun si iye ainipẹkun" (Johannu 4:14). O n sọ nipa igbala Rẹ̀, Ẹmi Rẹ̀ ti yoo maa gbe inu rẹ nigba ti obinrin naa ba yi pada. Awọn miiran ninu awọn Ọmọ Israẹli mọ riri bi omi lati inu apata yii ti ṣe pataki to nipa ti ẹmi, nitori Onisaamu wi pe "Nwọn si ranti pe, Ọlọrun li apata wọn" (Orin Dafidi 78:35). (Wo Deuteronomi 32:4, 15, 18, 31 pẹlu).

### Ogun

Awọn Ọmọ Israẹli ba iṣoro miiran pade nisisiyii. Awọn ọta jade lati ilu naa wa, lati bá wọn jà. Ẹya ti o ṣe pataki ju lọ ni aginju naa ni a n pe ni Amaleki. Wọn ni ẹtọ si ilẹ Kenaani, wọn si lero pe awọn ohun ini wọn yii wà ninu ewu nitori awọn Heberu dori kọ ibẹ. Wọn si tun le ti mọ pe awọn Ọmọ Israẹli ti kó iṣura lati Egipti wá wọn si fẹ ji i mọ wọn lọwọ. Ohunkohun ti o le jẹ idi rẹ̀, wọn wá si ẹyin agọ awọn Ọmọ Israẹli wọn si ba awọn alailera arinrin-ajo naa jagun.

A ni ohun titun lati sọ nipa igbesi-ayé ẹni kan nisisiyii, ẹni ti a oo gbọ́ pupọ nipa rẹ ninu itan igbesi-aye awọn Ọmọ Israẹli. Mose yan Joṣua lati jẹ ọgagun agba ti ẹgbẹ ọmọ-ogun wọn. A ranti pe ẹrú ni awọn Ọmọ Israẹli ti jẹ ri, wọn ko si ni ẹgbẹ ọmọ-ogun kan ri, ṣugbọn Mose paṣẹ fun Joṣua lati yan awọn eniyan ti o ba fẹ, ki o si jade lọ ba awọn ara Amaleki jà.

Jọṣua n bọ wa di ọgagun pataki. Lẹyin ikú Mose, o mu awọn Ọmọ Israẹli kọja odo Jọrdani ni ilẹ Kenaani nibi ti wọn yoo gbe jagun gba ilẹ naa. O ṣẹgun orilẹ-ède mẹfa ati ọba mọkanlelọgbọn laaarin ogun jija ọdun mẹfa. Lẹyin naa ni o pin Ilẹ Ileri naa laaarin awọn ẹya Israẹli. Idi rẹ̀ ti Jọṣua fi ni iṣẹgun nla bayii ni pe o tẹle Ọlọrun timọtimọ o si sọ ọrọ iwuri ti gbogbo eniyan mọ pe, "Bi o ṣe ti emi ati ile mi ni, OLUWA li awa o ma sìn" (Jọṣua 24:15). Igbagbọ ati igbẹkẹle rẹ̀ ninu Ọlọrun, ninu ohun gbogbo ni o fun un ni iṣẹgun. A ṣẹgun rẹ lẹẹkan ṣoṣo, eyi ni ni ogun Ai, eyi ti o kọ ọ lẹkọọ pe ohun pataki ni gbọran si Ọlọrun ninu ohun gbogbo.

### Iṣẹgun nipa Adura

Jọṣua kó awọn eniyan rẹ lọ si oju ogun; ṣugbọn bi wọn ti n ja lọwọ, ohun nla kan tun n ṣẹlẹ lori oke nitosi wọn. Mose ti goke lọ lati ṣọ́ ogun naa; bi o ba si ti n gbe ọpa Ọlọrun soke, ogun ti wọn a bori; ṣugbọn nigba ti o ba rẹ ọwọ rẹ̀, ti o si gbe apa rẹ̀ silẹ, awọn ara Amaleki a bori. Ọpa ti Mose n gbe soke Ọrun jẹ apẹẹrẹ adura. Lai si adura, awọn ọmọ-ogun naa ko le ni iṣẹgun rárá. A le maa ni ipade fun isin Ọlọrun; a le sọrọ nipa Kristi ti ijọba Rẹ̀, ṣugbọn bi gbogbo iṣẹ wa kò ba ni itilẹyin adura pupọ, ko ni mu eso kan wá rara fun Ọlọrun. Adura ni agbara ti o n ti ohun gbogbo ti a n ṣe fun Oluwa lẹyin.

Ṣugbọn arẹ mu Mose. Adura naa n mu aarẹ ba ara; ṣugbọn bi a kò ba gbadura ẹṣẹ yoo bori. Nihin ni a ri bi o ti ṣe pataki to fun gbogbo wa lati maa ran awọn olori wa lọwọ. Aaroni ati Huri ti goke lọ pẹlu Mose, wọn si jẹ ki o

joko si ibi kan nisisiyii wọn si duro si ẹ̀gbẹ́ ọtun ati si ẹ̀gbẹ́ osi rẹ̀, wọn si gbé ọwọ rẹ soke ni gbogbo ọjọ naa. Bayii ni wọn ran Mose lọwọ lati mu iṣẹgun wá fun awọn ọmọ-ogun wọn nipa adura, a si ṣẹgun awọn ara Amaleki.

**Egun lori Amaleki**

Awọn Ọmọ Israẹli ni lati maa ranti iṣẹgun yii, ati ki a ba le tọju iwe iranti yii fun iru-ọmọ wọn, o yẹ ki wọn kọ ọ sinu iwe kan. Ọlọrun gègun fun awọn ara Amaleki nitori wọn bá awọn eniyan Rẹ̀ jà, O si fẹ ki Jọṣua ranti pe a o pa wọn run ni ọjọ kan nitori ẹ̀ṣẹ wọn. Ẹ jẹ ki a ranti awọn ara Amaleki, ki a si ṣe akiyesi awọn ogun ti wọn ba orilẹ-ede yii jà ni ọjọ iwaju ati bi a ti pa wọn run patapata.

Mose tẹ́ pẹpẹ kan fun isin Ọlọrun, o si pe orukọ rẹ ni Jehofa-nissi – Jehofa Ọpagun mi. A ranti pe Abrahamu, Isaaki ati Jakọbu ti tẹ́ pẹpẹ fun Ọlọrun; ṣugbọn ni akoko igba ti awọn Ọmọ Israẹli wa ni Egipti, a kò gbọ nnkan kan nipa pẹpẹ rárá. Eyi ni ibẹrẹ igbesi-ayé titun ninu eyi ti awọn Heberu naa ni ibi ijọsin.

**AWỌN IBEERE**

1. Bawo ni awọn Ọmọ Israẹli ṣe le ri omi?
2. Taa ni apata naa?
3. Nibo ni a ti maa n ri omi iye?
4. Taa ni doju ija kọ awọn Ọmọ Israẹli? Njẹ wọn ṣẹgun?
5. Taa ni olori-ogun ẹgbẹ-ọmọ-ogun titun naa?
6. Bawo ni o ti ṣẹ́ ogun yii?
7. Ki ni yoo jẹ́ opin awọn ará Amaleki lẹyin ọ̀la?